William R. Bascom
Northwestern University

BASCOM
William Bascom, Director
Museum of Anthropology
University of California
Berkeley 4, California

# ETO ISIN

FUN

## EGBẸ AJUMỌKA ỌRỌ ỌLỌRUN.

1. Orin.
2. Ọrọ Ọlọrun.
3. Litani.

1. Ọlọrun, Baba Ọrun, ṣãnu fun wa, ẹ̀toṣi ẹlẹṣẹ.
   *Ọlọrun Baba Ọrun, ṣãnu fun wa, ẹ̀toṣi ẹlẹṣẹ.*

2. Ọlọrun Ọmọ, Olurapada araiye, ṣãnu fun wa, ẹ̀toṣi ẹlẹṣẹ.
   *Ọlọrun Ọmọ, Olurapada araiye, ṣãnu fun wa, ẹ̀toṣi ẹlẹṣẹ.*

3. Ọlọrun Ẹmi Mimọ́, ti o nti ọdọ Baba ati Ọmọ wa, ṣãnu fun wa, ẹ̀toṣi ẹlẹṣẹ.
   *Ọlọrun Ẹmi Mimọ, ti o nti ọdọ Baba ati Ọmọ wa, ṣãnu fun wa, ẹ̀toṣi ẹlẹṣẹ.*

4. Ẹni Mimọ Olubukun, Mẹtalọkan ologo, Ẹni Mẹta ṣugbọn Ọlọrun kanṣoṣo ṣãnu fun wa, ẹ̀toṣi ẹlẹṣẹ.
   *Ẹni Mimọ́ Olubukun, Mẹtalọkan ologo, Ẹni Mẹta ṣugbọn Ọlọrun kanṣoṣo ṣãnu fun wa, ẹ̀toṣi ẹlẹṣẹ.*

5. Fun gbogbo ẹṣẹ ati aiṣedede ewe wa bi ewe,
   "*Oluwa Rere, dariji wa, awa mbẹbẹ lọdọ Rẹ.*"

6. Lọwọ ẹ̀ro buburu gbogbo ati ifẹkufẹ ti ara,
   "*Oluwa Rere, gbà wa.*"